# IROHIN IMOLẸ

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAYA*

NO 871 MONDAY DECEMBER 14, 1964 (2D)

## "Akintọla Jẹ Aiye Tan"

IBADA:- Lẹ ulọlọyi ni awọn ọlọpa mu àwọn ọdaran mẹta kan Ganiyu Ajani Ayanyuni Ayinla ati Ajibade Amao ti nwọn nṣe iṣe ilu wa si ile ẹjọ fun ẹsun pe nwọn lu ilu ọtẹ nwọn si tun fi ilu wọn kọ orin owe eyi ti o le da ija nla silẹ larin ilu.

Ọlọpa ti o ba awọn enia na ṣe ẹjọ-ṣe alaye fun Adajọ agba ọgbẹni Tunji Go mesi wipe, ẹgbẹ Ilọsiwaju UPGA pari ipa de ti nwọn ṣe ni Mọlete tan ni alẹ ọjọ na.

Awọn onilu na nfi ilu wọn kọrin bayi pe, "ti o ba di ija, ṣe ẹ le duro? Ma fi ọwọ osi kan ọmọ mi, pawa, ọlowọ oro' Akintọla iaiye tan ẹ wo ẹrẹkẹ rẹ wand wandi"

Nigbati ọga awọn Ọlọpa gbọ ohun ti awon onilu na nwi' ni o ba paṣẹ pe ki awon olopa mu awon mẹtẹta.Ninu idajo rẹ adajo na so wipe, awon enia na jẹki ẹsun ti awon olopa mu won fun iwan hu le da ija igboro ilẹ.

Lẹhinna lo wa paṣẹ pe ki awon onilu na lo fi ponun mẹwa-mẹwa (£10 each)taarun si kotu, tabi ki nwon o lo fi ẹwon oṣu kookan jura ki ijina na o le jẹ arikogbon fun awon ẹlomiraa.

## Alhaji Adegbenro Sọ Pe :

# AWOLỌWỌ YIO DE SI EKO L'ỌJỌ KẸTA OṢU TI MBỌ

**EKO:— Gbogbo adugbo lokunṣọṣọ ti ko si si aye loju ona fun awon onimoto lati koja nigbati Alhaji D. S. Adegbenro Adele Asiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre wo ilu Eko gẹgẹbi Ọba ni osan ijẹta ojo Abamẹta ti ise ojo kejila oṣu yi.**

Ki ip de na to bẹrẹ ni deede agogo mejila ọsan ni gbogbo awọn obinrin ọlọja, Ebute-Ero, Jankara, Ereko Itafaji, Ọbun Eko Sangiros , ti pale ọju wọn mọ kuro ni oja ti nwọn si lọ pade Alhaji Adegbenro.

Pẹlu ilu ati ijo ohun orin ẹyẹ ni awọn obinrin ọlọja Eko fi njo kakiri gbogbo ilu Eko, t i u w ọ n si ba Alhaji Adegbenro lọ si ibiti o ti fẹ ṣe ipade pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ Ilọsiwaju UPGA

Nigbati Alhaji Adegbenro yio fi de, Tokunbọ, gbogbo Adugbo Amutọ ti kunṣọṣọ, t i awọn ọlọpa Ijọba Eko si nle awọn enia kuro iọna ki Aihaji Adegbenro to le r ave de ibi ti o ti fẹ ba awọn enia sọrọ

Orişirşi awọn ẹgbẹ ni nwọn wa nibi ipade na, lati wa gbọ ọrọ Alhaji Adegbenro.



**Oloye Obafẹmi Awolọwọ**
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Bi Alhaji Adegbenro ti nlọ, ariwo "Awo ! Awo!! Awo!!! lo gbojikan ti awọn enia na nkigbe bi enipe Awolọwọ wa nibi ipade na

AWOLỌWỌ

Ninu ọrọ rẹ, Alhaji Adegbenro dupẹ lọwọ gbogbo awọn ara Eko fun ifẹ ati ọyaya o h u n aniyan ti a w ọ n ara Eko ni si ẹ g b ẹ A f ẹ n i f ẹ r e o tun sọ siwaju si i wipe on mọ daju wipe awọn enia na nfẹ ri Oloye Ọbafemi Awo lọwọ Olori ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ.

Ṣugbọn ki o to sọrọ na tan, nwọn ko tilẹ jẹki o ti sọ tan, ti awọn enia na fi nkigbe 'Awo! Awo!! Awo!!!

Siwaju si i Alhaji Adegbenro fi gbogbo awọn enia na lọkan b lẹ o si tun fi ye wọn wipe ẹgbẹ Afẹnifẹre ki ise ileri ki o ma mu ileri na ṣẹ gbogbo ohunti awọn nsọ ni awọn yio se bi ẹgbẹ Ilọwaju ba wọle ninu ibo ti mbọ y.o.

Alhaji Adegbenro ni bi ẹgbẹ UPGA ba wọle, ni ọgbọn ọjọ oṣu yi, ti awọn si mọ aye ti gbogbo gbogbo oselu kọọkan wa, ki o to di ọjọ keji oṣu kini ọdun ti mbọ (1965) ni ojọ kẹta ọjọ Aiku ti işe ojo kẹta oşu kini ọdun ti mbọ ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ yio ba ọkọ ofurufu de si Eko

"Ni Ebute ọkọ ofurufu Ikẹja ni yio de si, nibẹ ni gbogbo awọn ọmọ ẹ g b ẹ Afẹnifẹre yio si ti lọ pade rẹ loju ọna pẹlu.

Bi o ti so bayi tan, ni ariwo nla ta ti awọn enia na si npe "Awo! A w o!! Awo !!!" fun ododi işeju medogun ni ariwo fi nta gee

Alhaji Adegbeuro na wa duro o nju iruke re funfun si gbogbo wọn, inu awọn enia na dun

Nigbati arwo na lọ silẹ Alhaji Adegbenro tun mba ọrọ rẹ lọ bi i pe;

"Nigbati Oloye Awolọwọ ba gun'le si ibudo ọkọ ofurufu Ikeja, lati ibe ni gbogbo euia yio ti tẹle lẹhin wa wọ ilu Eko ki o to tun sọ bayi tan ariwo tun ta gee.

Alhaji Adegbenro ni gbogbo awọn eto ati ti ẹyẹ ẹgbẹ

WO OJU EWE KẸFA



ALHAJI ADEGBENRO
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

## AKIYESI PATAKI

. Kini o nsare wa owo ti o fẹ fi ṣe ọdun kiri si? ṣe bi o ti gbo wipe Idije ẹbun orirẹ poun marun (£5) yio jade loni ninu Iwe Irohin Imọlẹ
2 Mase wahala kakiri mọ nigbati pọun marun (£5) na le jẹ tirẹ.
3. Mase duro de ọjọ ọla asiko ko duro de ẹnikan, ijafara lewu o.
4. Ki a ma wule jaapata mọ wo oju ewe kẹfa fun idije orire na ki o si tele kọwe si Olotu fun ẹbun owo tirẹ loni.

# Ibo Ilẹ Igbomina Ti Ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ni Iṣe

**Lati Ọwọ R. A SANUSI**
Akọwe Eto Irohin Ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre Igbomina

Eyi ni lati fi to gbogbo ẹnyin ọmọ ibile Igbomina leti pe ẹgbẹ UPGA ti ṣe tan lati gbọ ẹdun ọkan awọn ọmọ Ilẹ Igbomina ati lati da wọn lohun ohun daradara ti nwọn ba ṣe bere ti nwọn ba wọle ninu ibo apapọ ti o mbọ yi. Ẹgbẹ yi nikan ni o le se anfani fun ilẹ yi lai gba owo riba lọwọ ọnikan tab ṣe oju isaju fun orilẹ ede kan Ẹgbẹ ti o ṣe tan lati ṣe anfani aimoye fun orilẹ kakiri ilẹ Naijiria ni apapọ.



Ọgbẹni J. S. Ọlawoyin
Asiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ni Ilẹ Igbomina



DOKITA M. I. OKPARA
Olori Ẹgbẹ A'akukọ

Ẹgbẹ Olomi ni ẹgbẹ ti o ti nse Ijọba ni ilẹ Ariwa fun ọjọ pipe sẹhin bẹsini ko si ohun anfani kan ti nwọn se si ilu kan ni ilẹ Igbomina. Njẹ ti o ba jẹ pe ẹgbẹ otitọ ni ẹ ba se ti wọn se da Ilẹ Igbomina si, tabi mimọ ti a ko ti fbẹ jade ni. Mo fẹ ki gbogbo ẹnyin ọmọ ilẹ Igbomina jakejado ilẹ Naijiria mọ gbangba po ami 'Ake' Iwọn ẹniti nwọn yio gbe fun lati fi ṣe iṣẹ fun wọn ni nwọn nwa. Kosi si ẹniti nwọn le gbe fun bi ko se awọn ti nwọn ba fara mọ wọn ni orilẹ Igbomina Lati ọjọ ti awọn ẹgbẹ Olomi ti nse Ijọba wọn bọ nwọn ko se anfani kan fun Ile Igbomina. Ni igbati nwọn b ri pe kosi lebira ti o le se iṣẹ oko fun wọn mọ, kaka ki nwọn gba ọmọ ile yi si iṣẹ nwọn a si wa orisirisi ẹsun si wọn 'lẹṣẹ, nwọn a si ti ipa bayi da wọn si inu tubu lori ẹsun ti ko ni lari. Njẹ mo bere ẹnyin ọmọ Ilẹ Igbomina, ẹnyin ha ni nwọn kọ ọgba ẹwọn fun bi? Ọmọ ọdọ wọn melo lo wa nibẹ? Tabi ẹnyin ni kan ni ẹ mọ ọran da ni? Ara ikorira ati aikani kun ti a nto ka fun nyin ni eyi-kosi anfani kan ti ẹle bere lai na owo, ayọri eyi ti itu ja si ofo. Njẹ ẹgbẹ bayi ni o tọ ki ẹ tun tẹle bi? Nwọn ni ti era ba orin ni ti a ko ba tete gbọn nu' nṣe ni ifi ni pegi. Ti ẹnyin ko ba tete ronu daada kiẹ to se eyi ẹnyin yio kaba mọ re lẹhin ọla. Ti ẹyin sọ pe iya ti nwọn fi jẹ nyin l' dun marun sẹhin koti kosi ju pe ki ẹ ri ale kun re lọ ki Ọlọrun ko gba nyin lọwọ awọn ọdalẹ yi osi goe nyin leke wọn ni orukọ UPGA. Lotọ nwọn nda ẹru ba enia kakiri pẹlu orisirisi iya. Ṣugbọn mo fẹ ki ẹmọ pe ki eto le bọ a fi ti ẹba kọ ẹgbin si wọn ẹlu akin ọkan. Imọlẹ si ti pa ni ẹhinkule bayi. wNinu iwe irohin kan tiṣe Imọlẹ Owurọ ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni Ọgbẹni kan ti iṣe Alhaji Sanni Giwa ọkan ni u awọn ọmọ Ẹgbẹ Olomi-Ekọ, fi ye gbogbo onkawe pe ti J. S. Ọlawọyin ba to ki o wa sọrọ ni Ilẹ ọdọ rẹ. Mo fẹ ki ẹnyin onkawe mọ pe Ẹgbẹ eleto to peni Afẹnifẹre iṣe Yoruba a si mọ pa owe pe Ie ni akọ gba ki a to pa ita, boya irohin ṣeṣẹ kan Ọgbẹni yi ni nipa ipolowo Ibo Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ọgbẹni J S Ọlawọyin bẹrẹ lati ile lọ si o o Ẹgbẹ Afẹnifẹre ko jafara to yẹn Ko nṣe asiko yi lo ṣẹṣẹ yẹ pe ki Ẹgbẹ oto bẹrẹ ipolowo ibo Bakanna ni dun mọ ni ti Ọgbẹnina bale yor sita lehin ti Ẹgbẹ rẹ ba pari ipolowo ibo wọn tan nile Ẹgbẹ Afẹnifẹre Igbomina ti ti ile ko eṣọ to jade, ere oko ni yio si mu dari Ti Ọgbẹni Alhaji Sanni Giwa ba ka awọn ti o wa loko kun ki on na ba ọ sita ki o mọ bi on ṣe ni eto to.

Bakanna Irohin tori leti



OLOYE AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

iru owo nlala ti awọn Ẹgbẹ Olomi ẹkọ yi nna labẹlẹ, ẹnyin ko ha mọ pe owo ti aba fi ogun oju wa ko nṣe gbe Ẹ iẹ ki nwọn ma na iru fẹ owo na, abusi Edumare ni orukọ eyi iṣe fun awọn E iti nwọn ba gba wọn ba fu ko gba owo yi Gbogbo nyin sa ni e da owo Division ṣe ti ko ba sa bọ si mọ otito ni ki e gba owo nyin pada Ọlọrun ti ko pe owo nyin lo ni ṣegbe ni mo gb yin ui imọran ki ẹ gba owo nyin yi pada ki o to tan Ṣe ẹ kuku mọ pe aforu rin ni wọn ni asiko yi Njẹ ti erun ko ba r ba wọn e wo lo ha fa owo ikok I buburu ti nwọn ti ṣe lo nba wọn lẹru

Ni isiyi ọkan nyin ni ko je alufa nyin ki ẹ ma si ṣe foya Ẹgbẹ Afẹnfere ni yio bori ni gbogbo ile Igbomina eru lo n a wọn ti nwọn fi nja ijakuja bayi

E sa fi ọkan nyin balẹ bi UPGA Nwọn ni ti Egun ẹni ba jo re ara aya atọkan. Njẹ ti ba ṣe pe ododo ni Ijọba Olomi ṣe on to dara kalẹ lati ọdun maruu sẹhin, oju yio wa ti nwọn lati tu ile ọhun ka bi ẹgbẹ olokunkune ni ẹgbẹ Ol ni wọn ko s i l se ohun afani kan si ile Igbomina aya fi ẹgbẹ alafia ti iṣe UPGA ni o le m anfani owo ati alafia ba Ilẹ Igbomina Mo ke si gbogbo ẹnyin ti ẹ ba fẹ agbega orilẹ ede nyin lati so mọ ẹgbẹ UPGA sinsin Ki ẹ si ripe on ni ẹ di ibo in fun ti o ba di ọjọ ibo.

# IWE SI OLOTU

## A Nfẹ Ile Iwosan Nla ni Isẹyin

Olotu, Jọwọ gba mi ni aye die ninu iwe nyin oloyin mọmọ lati kesi Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati fun awa enia ilu ıṣẹyin ni ile iwosan nla eyi ti yio jẹ pe a ko ni ma lọ si Ọyọ ki a to le ṣe itọju ara wa.

Eleyi yio si dun inọ wa pupọ bi Minista Alamojuto eto ilera fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ba le lo ipo rẹ rere lati fi ṣe awọn nkan ti a bere yi ati paapa julọ awọn ọna ilu na ti ko dara lati rin fun awọn onimọto bayi.

Inu wa yio dun bi Minista na ba le lo ipo rere ati Olotu Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun lati tete da awa enia ilu Iseyin lohun iasiko a o si ma reti nitori awa enia Iseyin ko fi owo ori jafara rara.

Emi ni
Tayọ Olọpade
EKO,

## Awa LẹhinAwolọwọ

Olotu inu mi yio dun ti ẹ ba le ba mi tẹ iwe mi jade fun awọn ọmọ ilẹ Yoruba ẹ ro ori yin wo ki ẹ mọ ẹniti ẹ o Jibo fun nitori pe ẹgbe Dọmọnu eyiti iṣe ẹgbẹ Dọmọnu nwọn fẹ tan ọmọ Yoruba jẹ ati pe wọn fẹ tan awa ọmọ Yoruba fun awọn ẹgbẹ NPC ẹ ma ro owo ti ẹgbẹ NNDP eyi ti ṣe ẹgbẹ Dẹmọnu fun nyin ati ẹnyin ọmọ Oduduwa Ẹ rori jinlẹ ki ẹ dibo fun ẹgbẹ UPGA ki irọrun le wọ ilẹ Naijiria ki Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ le jade kuro lọgba Ẹwọn ki oju ti Ẹlẹgan, awa ọmọde ti Eko



ẹ flag awa si nṣe nkan pe fun awọn Agbalagba ki oloye Ọbafẹmi Awolọwọ olori ẹgbẹ Afẹnfẹre le jade ki irọrun le de fun ilẹ Naijiria ṣugbọn ki Oloye Ọbafẹmi ma bẹru oju ati Ẹlẹgan ki ẹ si ma ro ṣile marun ti awọn ẹgbẹ Dẹmọ ma fun nyin pe ki ẹju iwe sinu apo ti wọn ki ero ohun ti Awolọwọ ṣe si ilẹ Naijiria on ni o mu ile iwe ọfẹ wa si ilẹ wa Oloye Awolọwọ ni o si mu teli fi ṣan wa si Naijiria o si tun ṣe ileri pe ti on ba wọle ile we giga ofẹ wa ni ile Naijiria a ti

ile iwe fun awọn Dokita olotu mo dupe fun aye ti ẹ gba mi

E mi ni
Ọjẹdare Ọjediran
EKO

## Igbomina Eti Nyin Melo

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ bale gbami laye la'i kesi awọn ọmọ ilẹ Igbomina lati jẹki afiye awọn arufin Ijọba pe awa ki lṣe ọmọ ale atipe kie jẹki alọ si ile lasiko idibo to mbọ yi kia sidibo fun Ọgbẹni J. S Ọlawọyin kiasi gbede ipo ti awa ọmọ ilẹ Igbomina nfẹki Ọgbẹni wa



Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin

Mọfẹ fi ye awọn ọmọ ale Igbomina pe ibo ti afẹ di ẹ pe ki iṣẹ fun Ọgbẹni Ọlawọyin biko sepe fun eto gẹgẹbi ilọsiwaju atipe bi ilẹ wa yio fi duro gẹgẹbi Ọgbẹni wa Ọlawọyin bati bori ibo na.

Asiti nọpe Ọgbẹni Ọlawọyin yio ṣe oju wa gẹgẹbi ati nfẹ kio ṣe ni ilẹ Igbimọ asofin tio bade be atipe a lmọpe ọkan wato balẹ pe tio batide Igbimọ asofin pe ọkan awa ọmọ ile Igbomina siti balẹ dada nitori eyi ẹdibo fun Ọlawoyin

Emi ni
S M D Asuramu
ILHLA

## Ẹ Ma a Ka Iwe Iroein Imolẹ Lojojumo Fun Eto Ipolo wo Ibo


## Kini E Nduro Fun ?

Bi o ba ni asọ fun fifọ ati lilọ bi ( wollen) asọ oke, Tapẹta Sapẹti ati orişirişi asọ ti o ba ni fun fifọ ati lilọ ni iṣẹju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ
**JOYCELAUNDRETTE SERVCE**
**34, Ojo — Oniyun Street,**
**Apapa Road Ebute Mẹtta.**

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹsẹ kanna. A ie wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ọ ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranṣẹ si wa.
Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi iṣẹ wa ti dara to owo pọọku ni a si ngba



EGBOGI AWỌN ARA ILU FARANSE
# TESSYDRE
Fun Ọmọ — Ọwọ Ati Ọmọde Gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi haunhaun ti meji irufẹ rẹ kosi kakiri igboro ilu Nigeria fun itọju ọmọ ọwọ tabi ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu ẸHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aikole sun yala losan tabi sun awọn iya wọn gbogbo Ogorun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹro gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ şugbọn kosi eyi ta le fi we egbogi Tessydre rara o. Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn ara ilu Saro ati awọn ara ilu Agọnyin (CHANA) mọ egbogi yi dajudaju on na ni wọn si nlọ fun awọn ọmọ ti wọn ba ṣẹṣẹ bi titi fi di nkọn bi ọmẹ ọdun wawa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọka ori inu iwọ aiperi osiinu fẹkun fekun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ şişu, gburu tabi aikolokun ninu ara sisu, Inu kunkun iro afẹfẹfẹ ati orişirişi awọn amodi tabi aisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu nigba Ehin HIHU" gbogbo. Tessydre a ma mu ki ehin ẹnu rẹ ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati isan ara wọn pẹlu.

Awọn ọmọ ti wọn nlo egbogi yi ki saba şe amọdi rara niwọn igba ti wọn ba ti ngbọsẹ dede, ti otutu ko sI le ri aye lati duro ni igbaya wọn ti wọn jẹuo dara dara ti nwọn si nsun gbadun pẹlu

Bere Egbogi Ni Ṣọbu Awọn:—
WATERLOO STORES
8, Palm Church Street, Lagos
ADEDUN CHEMIST
4, Wakeman Street, Yaba

# Ayọ Ni Npa Enia

LATI ỌWỌ TUNDE ADESANYA

Ẹnyin ẹlẹgbẹ mo ro pe o to ọsẹ kan ti mo ba nyin jiroro lori eto ẹkọ wa sugbọn bayi mo si fẹ ki olukuluku nyin lọ mọ pe Keresimesi ti nsun mọ tosi bayi ati pe o yẹ fun olukuluku lati lọ ṣọra gidigidi nipa bi enikọ ọkan nyin yio ṣe lo ọdun Keresimesi ati ọdun titun to mbọ yi ati pe asiko isimi ni a si ma ni ile ẹkọ wa.

Nis'siyi ayọ ni npa enia nitori na ki ẹ ma ṣe je ki a yọ kọja gbogbo ohun ti ẹ o si ma ṣe tabi bi ayọ lo pọju nitori olukọ na ati baba mi ti sọ itan kan fun mi pe ayọ lo jẹ okan gidigidi to tete npa enia.

Ṣugbọn ẹnyin ẹlẹgbẹ mi Oluwa ma jẹ ki ayọ pa ẹni kankan fun obi wa. Nitori eyi ti o ba fẹ nyin ibọn a nṣire lasiko ọdun yi ma ṣe yin lu ẹnikẹni ki o si ni iṣọra gidigidi si gbogbo nkan ti ẹ ba nṣe lu ẹ ma ran awọn ẹgbọn nyin leti ki nwọ maṣe mu ọti a mupara tabiki nwọn hu iwa aṣeju nitori eleyi jẹ ọkan ni nu nkan tole fa ayọ eyito le tun mu iku pa enia.

Nitori eyi ẹnyin ẹlẹgbẹ mi ti e ba rigba isimi nyin lọsẹ yi kiẹ maṣe fi ayọ ba gbogbo nkan nyin jẹ pe ẹti yege ninu idanwo ti e ba ṣe kiẹ titori nafi eleyi hu iwa hu mosi fẹ ki ẹlọ ni ọkan a mumọra ṣugbọn ẹnyin ẹlẹgbẹ mi tikoba yege ise nyin ẹmaṣe ronu pupọ ju kiẹ silọ murasi ẹkọ nyin ti; bati wọ le kiẹle bori ninu ọdun bọsi laipẹ yi

Mo tun se ikilọ fun nyin pe kiẹ si rọra mafo oju ọna da larin tia wa yi nitori ọpọ lọpọ onimoto ni yio ẹba ayọ ninu ọti nitori idi eyi kiẹ sọra ni oju ọna kiẹ wo ọtun ati osi yin kiẹ tofo oju ọna da Odigba diẹ iyoku di ọsẹ o mbọ enyin elegb mi.

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Bi iyan jija ba ṣẹlẹ mu ọkan kuro kio wa nkan miran se.

PISCES (Feb 21- Mar 20 Gbogbo nkan mbẹ ni kawọ rẹ, kọwe si awọn ọre re.

ARIES (Mar 21- April 20) Akoko to fun ọ lati ṣe ohun ti o fẹ ṣe,

TAURUS (April 21 -May 20) Ipade kan yio ṣẹlẹ loni, iṣẹ re yio si ma lọ daradara.

GEMINI (May 21-June 20) Iṣẹ rẹ yio pọ loni, bi o ba si ṣiṣẹ na daradara ire yio de si ọ.

CANCER (June 22 -July 20) Ibikibi ti o ba lọ ni iwọ yio ma ba ire pade iwọ yio si yan ọrẹ titun.

LEO (July 23-Aug 22) Ọrọ kan yio ṣẹlẹ o si ri lati gbajumọ ọrọ na ki o ma bi fi iji i ẹ' laiṣe

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Edek oyede kan yio wa gbidanwo lati ṣe ẹtọ nibẹ

LIBRA Sept 24-Oct23 Aye ṣi silẹ fun ọ ti o ba fẹ gbe nkan titun miran jade.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 23) Aye wa fun ọ lati da iṣẹ miran silẹ ere pupọ si mbẹ fun ọ.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Nov 21) Iwọ yio ri ere pupọ jẹ lori iṣẹ rẹ.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 1) Iwọ yio niba rere pa.


# KERE O! Akiyesi Pataki

## Antoin Tablets ! Antoin Tablets !

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin, Mo ba yin ọ Ẹ ku afojuba egbogi pataki ti a ṣe iwadi rẹ lat. wọ awon Ọjọgbọn Oniṣegun (Specialist) Ilu Oyinbo Fun awọn ajakalẹ arun wọnyi:—

IGBONA:- Eyi jẹ Arun ti o ṣọpọ nisisiyi papa jul arun awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORI FIFỌ TULU LUKULUKU OTUTU IGBA AIYA ARA RIRO ati OTUTU ỌRẸRẸN pẹlu AKO-KORO Jẹwọ daiwo ajẹbidan ni ogun yi. Ireti hin ko afojuba Bere iwe ti ẹ o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta Egbog n fun nyin: O daju han un. Ẹ o ri iṣẹ rẹ lẹhin iṣẹju mẹdogun ti ẹ lọ. Bere lọwọ Oniṣegun adugbo rẹ.

*Distributors:-*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES

26, Bishop Street Phone;- 23745.

LAGOS

# Rọ Lọwọ Oso Ati Aje

we egbogi Ajẹbidan 25/- mejila £2
we Ilana Ifa Iyanrin titẹ ati etutumẹt pẹlu Iwe şan 20/-22/-ejila £2 5/
Iwe Egbogi Awogbo Arun meji 40/-
Turari iṣegun Ajẹ, Oṣo ati awọn aba nijẹ O wa fun itaja pelu alakala Pangolo 10/6- pakẹti 2-
Ki ṣe ti ẹnu fifọ i b o ri ninu awọn ọja yi aabo ti o nipọn ni ile i ve ii yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ
Fi owo ranṣẹ si

J. O. SHOYINKA
11, Alaba Street
Oduabọrẹ Mushin.

## Gbanjo ! Gbanjo

F N ỌDUN KERESIMESI

yi ni lati fi kede fun awọn oni bara wa pe Ọja gba- o wa bẹrẹ lati oni lọ titi di 30/11/64. Tete ra tirẹ o to kase nilẹ

APEJUWE ILE ITA IWE WA

Wọ Bọọsi Mushin, sọka'e ni Atẹwọlara Bus Stop ! Bere ladipọ Street, ti o ba rin titi Ladipọ, bere ILE IWE ODU - ABỌRE. Ti o ba de ibẹ tan, wa be re Nomba 5. Alaba Stree Mushin, ile iṣẹ wa dojukọti ODUS SURF"

AWỌN ỌJA WA

Olubori Egbogi Ajẹbidan 40s di 30s Iwe Egbogi Ajẹbidan 25s di 22s Iwe Egbogi Awogba Aruu 20s di 17s Iwe Ilana Ifa purin titẹ ati etu ṣiṣe 20s di 17 Iwe Afọṣẹ Isẹdale Yoruba ati Psalmu Ajẹbidan 3/6 di 2s 6d Tura i Isegun Aje 10s 6d di 8s Turari Itaja 10s di 6d 8s Turari Ala rere 10s 6d di 8s Iye owo Turari pangolo uiti oke yi Turari ti o wa ninu pakẹti jẹ 2s 6d pere Iwe Itumọ Ala Joseph Alala 5s Iwe Aniyan eto Irun o ti di 2s 6d Akọnni lesin pataki Islam 2s 6d Tailor's Measurement book di 1s 6d

Tenants Agreement Forms 10/6d di 5/ Gold Smith Form.s Certificate of Apprenticeship (meta) 17/6 di 10/6d

ỌJA TITUN TI A ṢEṢE RI GBA

Abẹla mimọ fun adura tete Idalẹju (ẹrişirişi awọ ti Turari.

Abẹla mimọ fun itaja (Kowo wole pẹlu Turari 20/-
" " Iṣegun " " pẹlu Turari 20/-
Lọfinda tabi Ororo ipara l n itaja, Iṣegun Ajẹ ati arisiki 30/- Igo kan

Fi owo ranṣẹ tabi ki o wa ra ni ọdọ:—

J. O. Shoyinka
5. Alaba Street
MUSHIN.

# Irinajo Mi Si Agbo Ile Ifẹlodun (Apa 5)

## Lati Ọwọ Ajẹgborodagba

Mo tun de bi nde ti ma emi ọ k ọ ibadiaran, mo ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin-Imọlẹ pe e ku ọjọ meta ẹ si ku eti i bọ ile Igbimọ Aṣofin Ap.pọ ti Dọkita Nnamdi Azikiwe tu ka ni ọsẹ to kọja.

Mo ro pe gbogbo yin ni o ranti ibiti mo ba irohin irinajo mi ni agbo ile ifẹlodun de, ṣugbọn ki on ma ba ọrọ mi r a lọ mo ni lati sọ fun nyin pe irohin mi na yio pari larin ọsẹ yi pelu i t a n igbesi aiye Oloye Gbelena.

Ni ọ j ọ kẹtala oṣu kẹwa ọdun yi ni gbogbo awọn ẹbi on nle jakejado ilu i j ọ m u Eko ati eka ti ile Kamarun pe ipade pataki kan si agbo ile Ifẹlodun ni nomba 25 I ṣ a g a Road Surulere lati jinroro lori bi ilọsiwaju yio ṣe wo fun gbogbo ọmọ ẹbi Gbenle ti o wa ri E k o ati kakiri origun mẹrẹrin aiye ati lati yan olori kan p ta-

Pillip o fẹrẹ jẹ p gbobogo awọn ẹbi na ko ti jẹ ki Alaga sọrọ yi dele ti awọn fi pariwo pe Phillip ! Phillip!! Phillip !!! wa ti fi aramọ on gan na ni a nfẹ ki o se Olori wa.

Lẹhin ti ẹdogb ẹbi ti ti gba ni Olori tan ni ẹdogbo wọn wa fi imọ sọkan lati ra awọn nkan oye bi Aṣọ ẹtu nla ilẹke yun yunkere lati fi da lọla nwọn bi kọ sile pe gbogbo ẹniti o ba ti jẹ oye Olori ni ẹbi yio ma ra awọn nkan nwọnyi lati fi da oluwarẹ lọla.

Ki ipade na to tuka, nwọn ko iwe ranse si Balẹ Ijọmu Oro lati fi han pe



Aworan ti ẹ nwo lẹke iwe yi ni ti igbati awọn ẹbi Oloye Phillip Afọ ayan Ajiboye Gbenle nmu b i lati wa silẹ nibiti nwọn yio ti ja ewe oye le lori. Ẹniti o wa ni ẹgbe osi Oloye na ni Amos Oyeyipo Gbenle. ti Ọgbẹni Martins Oyedepo si wa iẹgbẹ ọtun Oloye na

Ẹ KU AṢEYẸ ỌJỌ O.

ki fun gbogbo awọn ọ m ọ ẹbi Gbenle na.

I p a d e na bẹrẹ ni deede agogo meta ọsan ọjọ na ni abẹ alaga Ọgbẹni J a c o b Ibitoye Gbenle, lẹhin ti nwọn fi a d u r a si ipade na tan ni a l a g a wa sọ idi pataki ri o mu awọn pe ipade na.

Lẹhin ti gbogbo nwọn se asaro tan nwọn si fi imọ sọkan nwọn mu ọgbẹni wa yi Oloye Phillip Afọlayan Ajiboye Gbenle.

Nigba ti nwọn yan Ọgbẹni Gbenle ni Olori tan alaga wa bere boya a ri ẹniti ko fi ara mọ pe ki a yan

Ọgbẹni Phillip Afọlayan Ajiboye ni awọn yan gẹgẹbi ẹniti yio ma se Olori ebi awọn leko ati ni ilu Ijọmu Nwọn si fi iwe na ranse si Balẹ na Oloye Sule Akanbi Orimadegun Balẹ Ijọmu-Oro ni ọjọ kẹrinla osu kẹfa Ọdun yi.

Idunnu ṣubu lu ayọ, ayọ subu lu oyin fun gbogbo ẹbi Gbenle ati Oloye Phillip paapa ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu keje ọdọ yi nigbati nwọn ri iwe ayọ eyiti Balẹ Ijọmu Orimadegun fi da esi pada pe on ati gbogbo awọn ẹmewa on nihin fi ara mọ oye olori ẹbi Gbenle

O si tun gbadura pe ki Oluwa rere k i o ma dari Oloye na si ọna rere ti yio fi maṣe akoso ẹbi ati idile Gbenle nile ati loko, ki ade si pẹ ni o r i ki bata pẹ lẹsẹ ki ẹ ma si ṣe r i ẹjọ.

Nigbati o tun di ọjọ kẹta oṣu kẹjọ ọdun yi ti Balẹ Orimadegun si tun kọwe lati fi dupẹ nipa iranwọ a t i awọn nkan ti awọn ẹbi fi ranṣẹ si on fun ti iwuye na

Nigbati iwe aṣẹ si ti wa lati ọdọ Balẹ Ijọmu yi nl awọn ẹbi Gbenle s t i da ọjọ iwuye si ọna, nwọn si lọ si ile lọ ṣe inawo rẹpẹtẹ ti ko ṣe fẹnu sọ fun iwuye yi, ti o fi jẹ pe enia t i o ba nwọn lọ lati Eko ko se fi ẹnuso, lẹhin eyi ni nwọn ṣe wa se t i ilu Eko eyiti nwọn ṣe laipẹyi fun awọn enia ilu Eko ti nwọn jẹ ọrẹ a t i ojulumọ Oloye Phillip Gbenle

Nigbati mo nfi ọrọ wadi ti a fi Phillip j ẹ lati ọdọ awọn ebi rẹ.

ọ r ọ lẹnu Akọwe Oloye na ni ana ninu ọfisi rẹ nipa bo ya oye ti o jẹ yi bi o tilẹ ijẹ pe olori ẹbi idibo kan pataki nilu Ijọmu ni, njẹ yio ni anfani lati ma ba awọn gbimọ Ijọba ibilẹ ilu Ijomu joko nibi ipade ati ni awọn ile ẹjọ keke ti o jẹ ti Ijọba ilẹ.

Akọwe na si dahun o ni bẹni, ni iwọn igbati o jẹ oye idile pataki ni Ijọmu ati pe Baalẹ si ti fi aṣẹ si ti o si gba gegebi O l o y e kan pataki fun Ijomu-Oro o ni, o ni anfani lati ma ba wọn joko ṣugbọn bi o ti jẹ pe Eko ni ile iṣe Phllip wa. ko le ri aye ṣugbọn igba kugba ti o ba lọ si ile ni o ni anfani lati ma ba wọn joky pọ gẹgebi ọkan ninu igbimọ tabi adajọ.

Iya wa Esita Ogunbimpe Afọlabi, Oyewunmi. Abikoye Ranmi Adeoti Isahu Salami Badeji Macheal Ban dele Amosi Gbenle Kari-Gbenle, Ayọdele Gbenle, Okunloye Gbenle, Victoria Ona Ọlape Aisiki Afọlayan Ṣifau Adeoti Aṣihawu Ade oti, Yẹmisi Adewuyi, Orimadegun Balẹ

Eyi ni diẹ ninu orukọ awọn ẹbi Gbenle ti o wa nl bi ipade ọjọ na Mo tun wadi nipa itan Igbesi Oloye na, o si fun mi ni ẹkunrẹrẹ itan Igbesi aiye Oloye na lati igba ewe titi de iru Ipo ti o wa loni ṣugbọn ngo da iyẹn duro de ọtunla bi Oluwa ko ba kọ iṣẹ ẹru rẹ ẹ o ma ka itan na

O digba kan na o.

**Ipolowo Ọja Rẹ Ko Ti Yege**

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO ỌJA RẸ SINU

**IROHIN IMỌLẸ**

T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI ADVERTISMENT MANAGER

**IROHIN IMỌLẸ**

16, Bamgbọṣe Stre et Phone 21985

# IROHIN IMỌLE

*IMOLE ORE AIYE, T ENI GBOGBO LAWA*

No 871 MONDAY DECEMBER 14, 1964 [2D]


## Moto Meji Fori So Ara Won !

ILEESHA;- Jinnijini dabo gbogbo enia ti nwọn wa nitosi ni oju ọna Ile–Ifẹ si Ilesha ni kutukutu owurọ ana ọjọ aiku ti iṣe ọjọ kẹtala osu yi nigbati awọn mọto Akero meji kan fi ori sọ ara wọn ti awọn enia marun fi ku bamubamu.

Irohin awọn Ọlọpa asọmọto Ilesha fi ye wa pe, awọn mọto na nsare bọ lati pade ara wọn ni oju ọna ni nwọn ba fi ori sọ ara wọn ni Abuleko kan ti nwọn npe ni Ọshun.

Lẹskẹẹsẹ ti ijamba na ṣẹlẹ ni nwọn ranṣẹ si tẹṣan awọn ọlọpa, nigbati awọn ọlọpa de ni nwọn ba awọn enia na ninu agbara ẹjẹ, ti awọn mararun ti ku bamubamu.

Irohin na ṣe afikun wipe, awọn awamọto akero mejeji ko fi ara pa, ṣugbọn awọn mejeji na ti salọ ki awọn ọlọpa to de nwọn si fi awọn enia na silẹ nibẹ.

Awọn ọlọpa ti gbe oku awọn enia marun na lọ si ile iwosan lakulaku fun ayẹwo wọn si nwa awọn awamọto na lọwọ bayi.

Ki Oluwa gba wa lọwọ awọn awamọto sare o.

# AWỌN ỌMỌ ỌFFA ṢE IPADE

**EBUTE - MẸTTA:— Irohin ko to afojuba ni ipade ti gbogbo awọn ọmọ ibilẹ offa ti nwọn ngbe Eko ati agbegbe rẹ ṣe lẹnuloloyi ni nomba 45, Kadara Street, Ebute Mẹtta.**

Nigbati yio fi di agogo mẹta irọlẹ ọjọ na ni awọn enia ti bẹrẹsi de sinu ipade na lati Mushin, Shomolu, Apapa, Surulere, Ipọnri, Ilupeju ati ọgbẹ lọ.

Ninu ipade na gbogbo awọn ọmọ Ọffa ni nwọn fi ohun sọkan ti nwọn si gba wipe, o tọ o si yẹ ki awọn da ẹgbẹ ọmọ ibilẹ kan silẹ ni ilu Eko.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na gba wipe, ẹgbẹ na ki iṣe ẹgbẹ oṣelu, ko si ni fi ara mọ ẹgbẹ oṣelu kankan.

Ohun ti ẹgbẹ na yio wa fun ni lati maa wa ilọsiwaju ifẹ, isọkan ati idagbasoke ilu Ọffa ni ile ati ẹhin odi.

Bakanna ẹwẹ ni ẹgbẹ na yio ma a pese anfani ati ẹtọ ti o ba jẹ ti awọn ibilẹ Ọffa ile ati ni ẹhin odi ki ipade ọjọ na to pari awọn ọmọ ẹgbẹ na yan awọn oloye t tun fun ọdun yi ati fun ọdun ti mbọ yi,

Orukọ awọn oloye na ni wọnyi:-

Alaga ọgbẹni J. O Adedeji Igbakeji Alaga fun awọn ọmọ ẹgbẹ ti nwọn wa ni Ebute Mẹtta, ọgbẹni A. O. Belewu, Igbakeji alaga keji fun agbegbe Shomolu ọgbẹni Y. Ajibade, Igba kẹta Alaga fun agbegbe Mushin ọgbẹni J. Oyebanji Igbakeji alaga fun awọn enia Surulere ọgbẹni Y. Kọlawọle

Akọwe, Ọgbẹni S A. Adebiyi, Igbakeji akọwe kini Ọgbẹni J. Adewọle, Igbakeji akọwe keji Ọgbẹni J. M. Adewuyi, akọwe eto akọsilẹ owo, Ọgbẹni M. A Popoọla, Akapo Ọgbẹni S. A. Adedeji Akọwe eto inawo Ọgbẹni J. Alayande akọwe ipolowo ẹgbe ati Ọgbẹni S. O. Ọlagunju.

Lẹhinti nwọn ti yan awọn Oloye na tan, alaga, Ọgbẹni J O Adedeji dide, o si dupẹ lọwọ gbogbo awọn ọmọ-ẹgbẹ na fun wiwa ti nwọn wa si ipade ojọ na.

Lẹhin eyi ni awọn ọmọ ẹgbẹ na tun yan awọn enia mẹsan lati ma a ṣe igbimọ fun ẹgbẹ na Awọn enia mẹsan na ni wọnyi ọgbẹni Y A Lawal, ọgbẹni E A Amosu, J. B. Bakare, S. Okunlọla, S O Ọyawoye J. Afọlabi, Gbadamọṣi Popoọla, Alhaji Musatafa Ọlagunju ati dadipọ Fashade.

Agborọsọ awon omo ẹgbẹ na ti o ba oniwe irohin wa Ejongboro pada lana ṣe alaye pe, lati ojo ti awon ti yan awon oloye ati Igbimo ni eto ẹgbẹ na ti nlo deede ti awon ọmọ ẹgbẹ na si nwa si ipade dada.


## IDIJE! IDIJE!

A fi eyi kede fun awọn Onkawe Irohin Imọlẹ ati awọn Ọmọ karọ-o-jire pe a nfẹ

### ITAN L'EDE YORUBA

Ey.ti ẹnikẹni ko ti tẹ jade ninu iwe ri tabi ti nwọn ko ti sọ lori ẹrọ Rẹdio ri ẹnikẹni ti o ba si bori yio gba

**(£5)** PONUN MARUN

Akiyesi;- Kọ itan tirẹ kio han rekete, ti ẹniti koba han a o fa ya ni, ki o si mọ dajudaju pe ko ni ipa ninu Idijẹ na ti ITAN ẹniti o basi daraju ni a o ti jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ yi a o si fi (£5) Postal (Order) ranṣẹ si

Fi Stamp Tọrọ (3d) ranṣẹ fun gbigbe Pọnun marun (£5) ti o ba jẹ pada si ọ Ki o ge ibiti Idije yi wa, ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stamp tọrọ rẹ si wa ẹnikẹni ti ko ba ge Idijẹ tirẹ ranṣẹ siwa ti o ba jẹ owo na a ko ni fi ranṣẹ si.

Orukọ......................................................

Ibugbe......................................................

..............................................................

Fi itan rẹ ranṣẹ si:-

**Olotu Irohin Imọlẹ**
16, BAMGBOSE STREET, LAGOS.


## Awolọwọ Yio De Si Eko L'ọjọ Kẹta Oşu Ti Mbo

L ti Oju Ewe Kini

Ilọsiwaju yio ṣe fun ipadabọ Oloye Awolọwọ ni ọjọ na ni awọn yio ṣe ikede rẹ gbọ fun gbogbo aiye gbọ.

### AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ

Ki ipade na to pari' Alhaji Adegbenro fi awọn enia mẹrẹrin ti nwọn fẹ dibo yan ni ilu Eko han gbogbo awọn enia. Inu gbogbo wọn lo si dun lati ri awọn enia na.

Awọn enia mẹrẹrin na ni wọnyi: Ogbeni M. A. Bashua, Abiola Oshodi Shitta Bey ati Ogbẹni F. Moronu.

Alhaji Adegbenro wa kesi gbogbo awon enia na lati se akiyesi awon mẹrẹrin ti on fi won han ki nwon o si ri daju gbangba wipe gbogbo wọn lo wọle

Siwaju eyi ni Iyaafin S O Onabajo, ti ise Alaga awon obinrin ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Eko ki Alhaji Adegbenro ku abo ni oruko ẹgbẹ. o si ṣe iler wipe, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ mẹrẹrin ni yio wọle laiko si alatako kankan.

### IDAKẸ JẸJẸ

Lẹhinna ni Alhaji Adegbenro wa kesi gbogbo awọn enia lati duro, pẹlu idakẹ jẹẹ fun iranti iku ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre, Ọgbeni Amuda Anjọrin, to ku ninu ija kan ti o ṣẹlẹ ni ilu Ọta ninu oṣe to kọja yi.

Awọn enia na si duro fun iṣẹju marun laiko sọrọ


Printed And Published by Modupẹ Printing Press. 16 Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: (Olotu) TUNJI ADLỌSUN 45, Campbell Street Lagos (14/12/64)